# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KẸJỌ̀, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸJỌ 2021 – ṢE OHUN TUNTUN NÍNÚ AYÉ MI

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdáṣe |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

**Orin ibẹ̀rẹ̀**

1. Ósùn n'sà òkú Olùgbàlà mi
   N'dúró d'ọjọ́ tí mbọ̀ Olúwa mi

   Ègbè:
   Ní'bòji l'ójí dìde
   Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ
   Ò jíndè pẹ̀lú 'sẹ́gun lór'ókúnkùn
   Ó jọba títí pẹ̀l'áwọn ẹni mímọ́
   Ójìnde.............Ójìnde
   Allélúyàh! Krístì jíndè

2. Lásán l'asọ́ bòji, Olùgbàlà mí
   Lásán lay'ókùta dí bojì

   Ègbè:
   Ní'bòji l'ójí dìde
   Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ
   Ò jíndè pẹ̀lú 'sẹ́gun lór'ókúnkùn
   Ó jọba títí pẹ̀l'áwọn ẹni mímọ́
   Ójìnde.............Ójìnde
   Allélúyàh! Krístì jíndè

3. Ikú kòlè borí Olùgbàlà mí
   Ójá gbogbo ìdè, Olúwa mi

   Ègbè:
   Ní'bòji l'ójí dìde
   Pẹ̀lú sẹ́gun lórí ọ̀tá rẹ
   Ò jíndè pẹ̀lú 'sẹ́gun lór'ókúnkùn
   Ó jọba títí pẹ̀l'áwọn ẹni mímọ́
   Ójìnde.............Ójìnde
   Allélúyàh! Krístì jíndè

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Látònì lọ́, ìdibàjẹ́ òkùnkùn kì yóò tún lépa ayànmọ́ mi mọ́, yóò dópin lónìí , ní orúkọ Jésù.
2. Ọfàkọ́fà tí wọ́n ta sími láti tú mi sílẹ̀ fún ìyọnu, nípa agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, yóò fi ayé mi sílẹ̀ lónìí, yóò sì padà sọ́dọ̀ ẹni tó ran, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, dìde nípa àrá agbára Rẹ, jẹ gbogbo ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ àwọn ọ̀tá mi run, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí àwọn ọ̀tá mi di oúnjẹ fún ara wọn, ní orúkọ Jésù.
5. Iná itúsílẹ̀, dìde lónìi, pa gbogbo ààlè tí wọ́n ṣe lòdì sími run, ní orúkọ Jésù.
6. Ọlọ́run, dìde lónìí, fi àwọn ọ̀tá mi sínú àjálù tí wọn kò lè bọ́ kúrò nínú rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, nípa àánú Rẹ níbí lónìí, jẹ́ kí gbogbo ohun ìjà ogun àwọn ọ̀tá mi bẹ̀rẹ̀ síní dojú ìja kọ wọ́n, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.

3. Ọlọ́run, rán idarudapọ lòdì sí gbogbo agbára tí wọ́n yàn kó fayànmọ́ mi ṣòfò, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ìwé ìrántí, tí òkùnkùn ti fagilé lòdì sí mi, mo gbà ọ́ padà, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo alàjá mi tó wà nínú àgọ́ àwọn ọ̀tá, jáde nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí àrá Ọlọ́run pa gbogbo olùṣẹ̀dá ogun run nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Agbárákagbára tó gba àmì búburú láti pamí run, ya werè, ko sì kú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Orin Dáfídì 34:17:** Àwọn olódodo nké, Olúwa sì gbọ́, Ó sì yọ wọ́n jáde nínú ìṣẹ́ wọn gbogbo.

**Orin Dáfídì 107:6**: Nígbàná ni nwọ́n kígbe pe Olúwa nínú ìpọ́njú wọn, Ó sì yọ wọ́n kúrò nínú iṣẹ́ wọn.

**Orin Dáfídì 50:15:** Kí o sì képè mí ní ọjọ́ ìpọ́njú: èmi o gbà ọ́, ìwọ ó sì má yìn mí lógo.

**11 Sámúélì 22:2:** Ó sì wípé, Olúwa li àpáta mi; àti odi mi, àti olùgbàlà mi;

**Orin Dáfídì 34:4:** Èmi ṣe àfẹ́rí Olúwa, Ó sì gbóhùn mi; Ó sì gbà mí kúrò nínú gbogbo ìbẹ̀rù mi.

**Jákọ́bù 5:16:** Ẹ jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ nyín fún ara nyín, kí ẹ́ si mà gbàdúrà fún ara nyín, kí a lè mú nyín láradá. Iṣẹ́ tí àdúrà olódódo nṣe lí agbára púpọ̀.

**Jákọ́bù 4:7:** Nítorínà ẹ tẹríba fún Ọlọ́run. Ẹ kọ ojú ìjà sí Èṣù, òn ó sì sá kúrò lọ́dọ̀ nyín.

**Orin Dáfídì 77:14:** Ìwọ li Alágbára tí nṣe iṣẹ́ ìyanu: ìwọ li o ti fi ipá rẹ hàn nínú àwọn ènìà.

**Éfésù 3:16:** Kí òn kí ó lè fifún nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ ògo rẹ̀, kí a lè fi agbára rẹ̀ mú nyín lí okun nípa Ẹ̀mi rẹ níti ẹni inú;

**Éfésù 6:10:** Lákotán, ará mi, ẹ jẹ́ alágbára nínú Olúwa, àti nínú agbára ipá rẹ.

**Éfésù 1:23:** Èyítí íṣe ara rẹ̀, ẹkún ẹnití ó kún ohun gbogbo nínú ohún gbogbo.

**Orin Dáfídì 29:4:** Ohùn Olúwa lí agbára; ohùn Olúwa ní ọlánlá.

**Éfésù 3:20:** Njẹ́ ẹnití ó lè ṣe lọ́pọ̀lọpọ̀ ju gbogbo èyítí à mbérè tàbí tí a nrò lọ, gẹ́gẹ́ bí agbára ti nṣiṣẹ́ nínú wa.

**Míkà 3:8:** Ṣùgbọ́n nítotọ́ èmi kún fún agbára nípa ẹ̀mi Olúwa, àti fún ìdájọ́, àti fún ipá, láti sọ irékọjá Jákọ́bù fún u, àti láti sọ ẹ̀ṣẹ̀ Ísráẹ́lì fun u.